16 AUG 1965


# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA*

No. 1,425 TUESDAY AUGUST 10, 1965 (2D)


## WOLI KAN W'ẸWỌN OṢU MẸFA

ỌYỌ: Gbogbo enia to wa ni ile ẹjọ giga ti Ijọba ibilẹ ilu Ọyọ nigbati Ọkunrin Ọdaran kan ti o tun pe ara rẹ ni Woli fi ye ile ẹjọ pe on ṣẹṣẹ sa kuro l'ọgba ẹwọn ni atipe Woli Ojiṣẹ Ọlọrun ni on iṣe ni ile Ijọ ti a npe ni Kerubu ati Serafu ti ilu Ijẹbu-Ode, ọdaran na Ebenezer Aiyelabọla fi ye ile ẹjọ pe ohunti o mu on sa kuro l'ọgba ẹwọn nipe on ko fẹran lati ma a gbe lọgba ẹwọn.

Ninu ẹjọ ti Aiyelabọla fi ye ile ẹjọ na ni o ti rọ Adajọ lati ni oju anu fun on ati pe lati ọgba ẹwọn ni on ti sa kuro lori idajọ olejija ti ile ẹjọ fi kan on eyiti Adajọ ko ti iṣe ẹjọ rẹ ki on (Woli) na to sa kuro lọgba ẹwọn.

Ọdaran Woli na tun ṣe alaye fun ile ẹjọ pe nigbati on gbe oye wo ẹsun ti ile ẹjọ na fi kan on ni on ri mọ pe ile ẹjọ na ni lati paṣẹ pe ki on lọ si ẹwọn.

Woli na tun ṣe alaye siwaju sii pe nigbati on ri ọna ti on le gba sa kuro ninu ọgba ẹwọn na atipe onkosi fẹ ṣe ẹwọn ni on ba tete sa kuro ni Ọgba Ẹwọn na.

### Ẹ DA KUN

Lẹsẹkẹsẹ ti ọdaran na nba ọrọ rẹ lo ni Adajọ ile ẹjọ giga ti Ijọba Ibilẹ na ọgbẹni Yẹmi Orafidiya ti da Woli na lohun pe "bi o ba mọ wipe iwọ ko laiya lati lọ si Ọgba ẹwọn, o ni iba san fun on ki o maṣe lọ fa nkan ti ọwọ rẹ ko le gba tabi ki o maṣe lọ jale".

WO OJU EWE KẸFA

# IJỌBA FẸ GBE ẸJỌ ỌRẸDẸIN KURO NI'JẸBU ODE?

IBADAN Gbẹgẹdẹ gbina ninu ile ẹjọ ganran Ibadan nigbati awon Ọlọpa ko awon enia kan ti Ijọba nba ṣe ẹjọ ipania wa siwaju adajọ agba Ipinlẹ Iwọ Orun ninu ile ẹjọ ganran Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria niwaju ọlọla Adeyinka Morgan ni ana ọjọ Aje ti ise ọjọ kẹsan oṣu yi lori ẹsun Ipania.

Ọgbẹni Tajudeen Oki ẹniti iṣe Olori gbogbo awọn agbẹjoro fun Ijọba Ipinle Iwọ Orun Naijiria ṣe alaye wipe on gbe ẹjọ na kuro ni Ile ẹjọ giga Ijẹbu-Ode ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi nitoripe awọn enia na ko ni ri idajọ rere gba ninu ile ẹjọ na ti adajọ agba ti nṣe ẹjọ na ọgbẹni Moses Tunji Oyemade ba ṣe ẹjọ na.

Ọgbẹni Oki tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, gbogbo awọn ẹlẹri ti awọn Ọlọpa ti pe lati wa jẹri ninu ile ẹjọ na ni nwọn ko tun fẹ wa jẹri ninu ile ẹjọ na mọ.

Ọgbẹni Oki ni nitori eyi ni Ijọba ṣe gbe ẹjọ na kuro ninu ile ẹjọ na ti Ijọba ko si fẹ ki adajọ na ṣe ẹjọ na mọ awọn si ti gbe ẹjọ na kuro.

Nisisiyi, Ijọba ti gbe ẹjọ na kuro, ṣugbọn on nrọ adajọ agba fun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọlọla Adeyinka Morgan, wipe ki o gba fun Ijọba lati le gbe ejo na kuro ninu ile ejo Ijẹbu-Ode ki awon si le ṣe ejo na ni ile ejo Ibadan.

Ṣugbọn Ọgbẹni Olu Ayọọla, ẹniti iṣe olori awọn agbẹjọro fun awọn enia ti Ijọba nba ṣe ẹjọ sọ fun adajọ ile ejo na Ọlọla Adeyinka Morgan, wipe ki o

WO OJU EWE KẸFA

## MỌTO KAN KOSI ẸNU OKO RELUWE

MUSHIN:- Jinnijinni dabo gbogba awọn enia ti nwọn wa ni tosi nigbati nwọn gburo mọto akero kan nọmba L C 9606 fẹ sare kọja ọju ọna ọkọ reluwe Mushin, ti mọto akero na si ko si ẹnu ọkọ reluwe kan ti o nbọ lati Eko ni deede agogo mẹsan owurọ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keje oṣu yi.

Oniwe irohin wa ti ọrọ na ṣ'oju rẹ fi ye wa wipe, nigbati mọto na fẹ sare kọja loju ọna, lẹhinti o ti gburo wipe ọkọ reluwe nbọ' ṣugbọn ki o to sare kuro ni oju ọna tan, ọkọ reluwe na ti de, o si gbe mọto na kuro ni oju ọna pẹlu awọn ero mẹfa ti nwọn wa ninu mọto na pẹlu ẹni, ẹniti o nwa mọto na.



Bi ọkọ reluwe na ti gbe mọto na ni agbedemeji tan ni ariwo ba ta gee, ti gbogbo igboro ilu Mushin si gbojikan fun ariwo, nigbati ọkọ reluwe na gbe mọto na ti o si ngbee lọ ti ko duro.

Nigbati ọkọ reluwe na gbe moto akero na nilẹ o si gbe kọja ẹsẹ bata mejilelogoji ki ọkọ reluwa na to le duro ti o si ngbe mọto na lọ

Ṣugbọn gbogbo awọn enia mẹfa ti nwọn wa ninu mọto na ni nwọn ko fi ara pa titi ọkọ reluwe na fi gbe mọto wọn duro nwọn si sọkalẹ layọ ati alafia ṣugbọn mọto wọn bajẹ rekọja idaji.

Gbogbo awọn ero ti nwọn fẹ wọ ọkọ reluwe kuro ni Eko ni ọjọ na ni nwon duro si Iddo ti nwọn ko si tete ri ọna gba kọja si Ibadan tabi Abẹokuta, ṣugbọn lẹhin nkan bi wakati mẹrin ti awọn oṣiṣẹ na *ti bẹrẹ*si ṣe iṣẹ wọn *ni* nwọn to le pari iṣẹ na ti nwon si ko akisa mọto yoku kuro ni oju irin.

Oju ọna Mushin ti o bajẹ lo jẹki awọn mọto maa lọ gba oju ọna na, ṣugbọn ni akoko ti mọto na fi ko si ẹnu mọto, obi gbanja lo wa ninu mọto na ki iṣe enia lo ko,

Ki Oluwa ma jẹki a rin ni ọjọ ti ebi npa ọna o,

# Iwe si Olotu Irohin Imolẹ

## Iwe Irohin Dẹmo" Ha Ni Irohin Imolẹ Iṣẹ Bi?

Iba dara pupọ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le fi ye awọn Onikawe iwe Irohin rẹ ni Ibadan bi Ẹgbẹ "Dẹmọ" ni nwọn ba nṣe atọkun rẹ tabi ẹgbẹ Ọlọpa.

Nkan to mu mi bere bẹẹ ni pe otitọ irohin kan ki ija de ninu iwe ti o ngbẹnuso fun ẹgbẹ Demo ti oruko rẹ njẹ "Imolẹ owuro"

Oruko ti mejeji to papo mo ara won yi kojẹ k'awon ara Ibadan ni ifẹ si ati mara iwe Irohin Imole ntoripe nwon ṣebi ọkanṣoṣo ni on ati iwe irohin Dẹmọ nitori idi eyi mo daa ni imoranpe ki ẹ yi oruko iwe irohin ti yin pada si Irohin Odua, Ẹ dakun ẹ maṣe ba judasi jẹ oruko pọ.

Emi ni
Sunday Ogundipẹ
Inu enoae, Ibadan.

## Mushin nfẹ Atunṣe

Olotu Jọwọ gba mi laiye ninu iwe rẹ oloyin mọmọ la ti bẹ awon Alamojuto Igbimọ Ijọba ibilẹ Mushin pe ki nwọn jọwọ lasiko ti ojo da wọ duro die yi ki nwọn gba ara nwọn niyanju lati le mọ bi nwọn yio ṣe da si a won opopo (Street) ti o wa larin ilu Mushin ati Shomolu.

[illegible] taki julọ ninu awọn igbimọ ibilẹ Mushin ni oriṣiriṣi anfani lọpọlọpọ ti awon omiran ọna abiya si Yaba si Ikorodu Road ti bẹbẹ [illegible] a si ropẹ ti nwọn aba k[illegible] bi ọn si awọn iruf ọ a wọnyi opopo Agẹgẹ mọto le dar[illegible] ju bi o ti ṣewe tẹlẹ si inu awa olugbe Mushin yio dun lopọlọpọ ti ijọba ibilẹ ba le ṣe eyi fun wa fun itẹsiwaju nitori pupọ ninu awọn olugbe Mushin lo ti ko kuro lori o a ti ko d[illegible]r.

Emi ni
Abikẹ Kaffo, Mushin

## Ijoba Ibilẹ Eko

Olotu:- Jọwọ gba mi laye ninu iwe rẹ oloyin mọmọ lati kesi Ijọba Ibilẹ Ek.

Ikesi mi na ni wipe ki nwọn jọwọ fun awa olugbe Mushin ni Bọọsi ti yio ma de arin ilu Mushin Yaba ki nwọn ma gba Isọlọ, PALM Avenue, Ladipọ Street nitori ile pọ bi rẹrẹ larin Mushin omiran to ibusọ meta mẹrin ati ma ransi idi Bọọsi eyiti o nma mu irẹ mẹsl ba awa olugbe nigbakugba ti a ba fẹ lo sode oko gbodọ lọ ṣode ni alẹ ni tori idi eyi a bẹ Lagos City Council wipe nigbakugba ti nwọn o ba ṣe ipade nwọn ki nwọn ba fi eyi sero tabi ki Ijọba Ibilẹ ṣe anfani fun awọn mọto moluẹ ki nwọn ki o ma de papa Ajao lati le ma ko awa olugbe ibẹ lo sibi kibi ti a ba fẹ lo ti nwon o si ko wa pada bakan na.

Olotu o ṣe o.

Emi ni
Iyabọde Maan

## Ẹ Ma Gbagbe Wa O

Mba sope bi Olotu ba le gba mi laye lati kesi awon Alaṣẹ Ijoba Ibilẹ wa Ajassẹ Ipo ati papa julo Ijoba Ipinlẹ Ariwa pe ki awon jowo afara Odo Oshin ṣe eyiti o so Oke Ode ati Omu Aran.

Otito nkan bi ọgọta odun sẹhin nisisiyi ti nwon ti ṣe a'ara odo na. Afara na si ti gbo to bẹ gẹ e ti o fi jẹ pe pelu inu tosẹdo fun awon Onimoto fi nsoda Odo ni

Eleyi si jẹ ewu fun gbo gbo enia nitoripe ẹmi ko laaro, to ba ja l o ṣe so.

Inu wa yio dun ti Ijoba rere na ba lo se afara oda na fun wa laipẹ, ki a le ku ro ninu ewu.

Olotu, Mo dupẹ O.

Emi ni
Saidi Olupo
Ajassẹ Ipo


## Anfani Nla De Fun Gbogbo Awọn Ti Nlo Gulu

TI A FI NLẸ PAKO TABI IWE

Gulu Funfun eyiti a ti ṣe wa lati ilu Oyinbo ti o wa ninu Igo Funfun oorun rẹ dabi lọfinda ti a nbu sara Irohin ko to afojuba tete yara lọ ra tirẹ lọdọ :

**Y, AROWOLO NI 118, Griffth Street, E. B Lagos**

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igo kekere | 6/- | Igo Nla | 8/- |
| Igo mejila nla | £4 4/- | Igo Kekere | £3 |



# Bọ Lọwọ Oṣo Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/- mejila £2 5/-
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari isẹgun Ajẹ Oṣo ati awon abanije O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/- Pakẹti 2/- Ki iṣe ti enu fifọn bi ara ninu awọn ọja yi aabo ti o nipọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ebi rẹ.

Fi owo ranṣẹ si
J O SHOYINKA
15, Alaba Street
Odunbọrẹ Mushin.



EGBOGI AWỌN ILU FARANSE

# TESSYDRE

Fun Ọmọ—Ọwọ ati Ọmọde gbogbo





Tessydre jẹ ojulowo egbogi hanuhaun ti meji irufẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Naijiria fun itọju ọmọ ọwọ ati ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aiko le sun yala lọsan fun awọn iya wọn gbogbo Ọgọrun oriṣiriṣi egbogi bayi ni wọn npolowo ninu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumo ṣugbọ ko si eyi ta le fi we egbogi Tessydre rara o, Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awon ara ilu Saro ati awọn Agọnyin (GHANA) mọ egbogi yi dajudaju on ni awọn si nlo fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkan bi ọmọ ọdun mẹwa gbako . Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọ a ori aiperi ori inu iwọ osi fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ ṣiṣan gburu tabi aisi lokun ninu ara, sisu Inu kun nun aiorun ati orisirisi awon amodi tabi aisan ti o ma eyọ awon ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU gbogbo Tessydre a ma mu ki ehin ẹnu ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati san pẹlu.

Awọn ọmo ti o nlo egbogi yi ki saba ma ṣa rẹ rara niwọn igbati nwon ba ti nlo deede, ti otutu ki si le ri aye ati duro ni igbaiya wọn ti wọn njẹun daradara nwon sun gbadun pẹlu yio si jẹ ki erigi san pẹlu.

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

# Egbe Oșișe [illegible] Awon Alakoso Ile Ișe Dunlop

IKEJA:- Ninu irohin kan to de owo wa ni Ojo Eti ti ișe ojo kefa osu yi ti irohin na fi ye wa pe awon egbe osiși șe ti a npe ni United Labour Congress ki lo fun awon Alakoso ile ișe Dunlop ti nșe Taya keke ati moto ni Ikeja lati tete da awon osișe won lohun lori ohunti nwon ubere lowo awon Alakoso ile ișe na ati pe ki nwon tete pari edeaiyede to wa larin awon oșișe ti nwon to 50,000 pelu awon Alakoso ile ișe na.

Ninu ipade kan ti olori egbe awon oșișe ogbeni L. A. Borha ba awon oniwe irohin șe ni o ti șe alaye pe bi awon Alakoso ile ișe na ba kuna lati șe eto to wa larin awon pelu oșișe o ni yio da ohunti o je wipe gbogbo awon oșișe won ni jake-jado ni yio binu da ișe silę.

Oniwe irohin wa ka ran wa leti pe o di ojo ketadin logun ti awon oșișe na ti binu da ișe sile.

Ninu awon ohunti o mu ki awon osișe ile ișe na da ișe sile ni owo ooya lori moto ti awon oșișe na ma na owo wa sibi ișe ati owo isimi lenu ișe pelu owo to ki yo awon Alakoso ma san fun awon osișe lehin ti ba ti pari ișe ti nwo tun șișe wakati merin.

Oniirohin wa to lo si ibi ișe awon Dunlop ni Ikeja nibi ti awon osișe na ti binu da șe silę fi ye Wa ninu irohin re pe egbe awon osiișe ti ile ișe na pelu egbe osiișe ti a npe ni United Labour Congress.

Ninu oro olori egbe awon osișe ti United Labour Congress Ogbeni L. A. Borha tun bu etu ate lu iwa ti awon Olope nhu si awon osișe to binu da ișe sile ta lori ki nwon ma le awon osișe na tabi pe ki nwon ma a d'eru ba awon oșișe na lori eto won ti nwon nja fun.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Mașe fowo le ișe ti tun ka loni bi beko iwo ko ni le gbe ișe na dori ki o to ju ogo nu

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Mașe je ologbon loju ara re feti sile si ibawi nitoripe ninu re ni opo ire wa fun o

ARIES (Mar 21 - April 20) Ire ni gbogbo ojo oni yio je fun o ati idunnu ko si ewu tabi idamu kan fun o

TAURUS (April 21 May 20) Aare ati idamu yio fi owo ba o die, șugbon bi o ba di ri ojoro, alafia yio gbile

GEMINI (May 21 June 21) Mașe bere awon ohun ti o nira lori, șugbon bi o ba le șe suru ki ire su nkan yio je suru fun o

CANCER (June 22 July 22) Nse ni ki o se waha la ki owo re to le te ișe kan loni, ire wa ti o nduro de o

LEO (July 22 - Aug 22) Șora nitoripe iwo le e șikan ti ko fi nkan pe kan bi o ba te nse be re mașe se be loni

VIRGO (Aug 23 - Sept 23, Ore re kan yio șe ore ti ko ni gbagbe fun o nitori re bi yio si șowo [illegible]

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Obirin pataki nfe lati ba o șe ore ti o ba mota, tire ni obinrin na yio je

SCOPIO (Oct 24 - Nov 22) Inwe re ti o ni si gbogbo eni yio fa ire [illegible] wa ba o lopolopo

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Mașe ba eni ta bi ki o dapara la enia loni, bi beko nwon o lori re nwon yio si tuna ayin re.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Inu mbi eya re si o, bi o ba kowe sile loni nwon ko ni fun o lesi

GBANGBA DEKUN! KEDERE BEWO!! BI INA WOLE OKUNKUN YIO PARADA IYE N DAJU




BERE EGBOGI TUNTUN TI WON NPE NI:—

## "DROSELA"

Meji re ko si ni igboro Ilu Eko tabi Nigerie lenu n Bi amodi "IKO" ti ojo re ti pe tabi ti o npo robiroși nkan bi odun kan tabi jube lo, awon egbogi se iwosan won nla kakiri tabi ipolowo ni orișirisi ko lo re rara, ma fi owo re șe ofo mo.

Bere fun egbogi won ara ilu Faranșe ti nwon np ni "DROSELA" oju owo haunhaun atamatase ege fun Iko egbe Iko Aiperi, Iko Awujo on Iko Awu ogun Iko ononfun, iko lile. Iko ti o mo mu enia ti ebe nigba kugbo Itinu " Ifun wa (Lungs) tabi ti o n mu enia ru pelu. Bi o ba dan Igo kan DROSELA wo Iwo na yio ri iyato ninu ara re ni kiakia Igba aya ti bi ona ofun re ti o ma nho yio duro "IKO" re yio sisan patapata iwo yio si ma a jeun daradara, iwo yio si suu fon fon pelu, alafia de si o. Bere egbogi yi ati awon orișiriși Egbogi Iko miran ni Șobu awon:-

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 2287 Nigeria (Oja Ita Faji)
ATI NI ȘOBU
IȘE OLODUMARE DISPENSARY OKEBOLA
IBADAN
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba.

## 'UROYSAN DRAGESS'

on itojutabi fifo iAro Ile Ito (Kidney Blinder) fun okunrin tabi obinrin bi awon amodi wonyi ba nyo o lenu orunkun, Ibadi, Gige tabi riro eri ito, tabi ito jijo enia ito inun rukurusu Pipon aikoleri ito to lakuregbe orunkun owo ese Eji a wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobi aiko le gbe ra konkon tabi kiakia didaju arinigbakugba ati o ișirisi awon aisan tabi amodi wonyi ni egbogi ajebidan yi yio wo san lara re ni kiakia ti alafia yio si de si o. Meji re si ni ilu Najiria nitorina sora ki awon eleru tabi awon onibiroko ma ta orisi miran ni kon fun o, mașe gba rara! Owo re je Sile mefa abo 6/6d owo Owo sile kan ati abo (1/6d.)



NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Laos

# Itan Orişa Awọn Ibeji

### Lati Ọwo ẸṢỌ

Odu ifa kan so fun wa pe ni ọjọ kan ifa ati Olodumare lọ si ajo, ki nwọn to de ọhun ilẹ ṣu awọn mejeji si jin sinu ofin, ni alẹ ojọ na, ojo ro o si fa agbara ọjọ awọn mejeji ko le jade igba na ni Olodumare wi fun Ifa pe ki o ru, Ifa papa wi fun Olodumare pe ki o ru, awọn mejeji gbọ, nwọn ru, nwọn tubọ, nwọn şe etutu, nigba yi ni ebi wa bẹrẹ si pa awọn mejeji.

Nwon ri Ira oniwo kan, nwọn kesi pe ki o yọ wọn jade, Ira kan ngbọ ohun ni ko mọ ẹniti o mba on so rọ, o dahun pe ira'owọ ki ni on yio şe, on ko'e jẹki ọrọ ọlarọ wa di ti on, bi on ba pe ki on yọ wọn jade Ibẹ ri ọdẹ ti ọgbẹ ọfin silẹ de wa ba on, yio si pa on bayi ni Ira si ba tirẹ lọ, Agbalangbo mejindi lo un bakan ni o wi, o si ba ti rẹ lọ, Ẹkun, Erin, Ẹfọn, Gidigidi, Ijakumọ, Esuro ati awọn eranko bi Imado.

Bi Ẹdun ti fo lati origi kan si ekeji bẹni o tọ kan ti o ri Ira ninu ofin, oja Ibo o jun si Olodumare ati Ifa bẹrẹsi jẹ, Ẹdun ke suwọn pe kini ohun ti o gbe wọn de inu ofin? nwọn rohin fun tan, nwọn ni ki o yọ wọn jade ninu ofin na, Ẹdun fi ọwọ rẹ mu igi dani, o si na iru rẹ sinu ọfin, o fi yọ awọn mejeji jade ninu ọfin na.

Nigbati nwọn de e, Ifa Olodumare wa lọ ti ara wọn mọ ile Ikomọ lode orun, oşu kini koja, oşu keji koja nwọn ko ri ifa, nwọn ko ri Olodumare. Nwọn pe Agbọnrin ki o wa lọ şilẹkun ile Ikomọ. Agbọn lọ o si kan ilẹkun ile Ikomọ ka, ka, ka, le, le le! Ifa bere wipe, iwọ yesi nkan ilẹkun ka, ka, ka, yesi nkan ilẹkun ọşin le, le, le? Agbọnrin dahun wipe, emi Agbọnrin igboro, abiwo daw ro dawọro. Nigbana ni Ifa wi fun pe pada sẹhin iwọ agbọnrin Igboro, abiwo gbajagbaja abiwo gbeje-gbeje iwọ mọ igba na ni, tabi o ba wọn wọ ile Ikomọ ri afara dẹhin.

Bayi ni a ko ri ẹniti o le şilẹkun ile Igboro, nwọn wa n'eri silẹ de ẹni ti yio wa şilẹkun na, gbogbo ẹranko lo şilẹkun na ni aşiti, ecbu ati isosi ni nwọn ngba ni dirẹ Nigbati o şe ni Ẹdun de o kan lẹkun ka, ka, le, le, le, Ifa bere wipe yesi nkanlẹkun Ọşin ka ka ka, yesi nkanlẹkun ọşin le, le, le? O si dahun wipe, emi Ẹdun ni, Ifa jagbe mọ wipe kai! pada sẹhun, iwọ Ẹdun ọlọwọ pọjọ pọjọ. ẹlẹsẹ pọjọ pọjọ, olojufoki foki, pada si ọhun, iwọ ha mọ igba na, tabi iwọ ha ba wọn wọle Ikomọ ri?

Nigbana ni Ẹdun wa bẹrẹ si rahun wide, ẹhẹn! bẹ ni ọrọ wa da? oju mi foki foki yi, ni mo fi ka Ibo fun Ọlofin jẹ ni, ọwọ ni fọjọ fọjọ fọjọ yi ni mo fi ka ilo fun Ọlofin jẹ ri.

Ẹsẹ mi pọjọ pọjọ yi ni mo fi ka ibo fun Ọlofin mu ri. Nigbati Ifa gbọ bẹ, o yi ohun pada, o wipe, he! o to pẹlẹ maşe tun irohin mọ Ẹdun ọlọwọ pọjọ, Ẹdun ẹlẹsẹ pọjọ, şilẹkun ki o wọle. Bayi ni Ẹdun ba wọle Ikomọ.

Nitorina bi a ba de yin mọ enia ninu, Orişa ileji ni o le tu silẹ.


## Ipolowo Oja Rẹ ko Ti Yege

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ

**SINU IWE IROHIN IMỌLE**

I'ODUNKA FUN GBOGBO ENIA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
ADVERTISEMENT MANAGER

**IROHIN IMỌLẸ**

16 Bamgbose Street, Phone 21985 Lagos



**[illegible]**

Aworan egbọ yi fi han gba ngba ibiti jẹdijẹdi to wa lara rẹ ti nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo Ibẹ ni a npe ni omusu tabi iho idi enia ibiti ẹ ma ngba işẹ igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ikan ninu amodi ti o buru, ni pataki fun okunrin ti o si şoro pupọ lati şe iwosan rẹ tan patapata.


CYCLOVEN

Ọpọlọpọ egbogi li owa tia nta kakiri ode isisiyi ti awọn ma npolowo nwọn fun iwosan rẹ şugbọn boya ni a le ri mẹwa ninu awọn ogun to le şe iwosan arun na daradara.

Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn gbe lo si ile iwosan lati lo ge eyiti o ba nyo jade ni omusu on nipa bẹ awọn yio bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa koro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa Ebini ti o bẹrẹ aiko maşe igbọnsẹ deede tabi lojojumọ, gigun kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹ'omiran ẹwu ẹran Suga onirutu ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba jẹdijẹdi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ma nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnşe tabi ti nrin ọ ninu omusu rẹ ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCOVEN ti awọn Oyinbo Jamani şeşe wa idi rẹ ki o si dan wo o ri daju wipe iwọ yio bọ lọwọ jẹdijẹdi patapata ti a ta nigboro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji



BERE EGBOGI ARỌN

## VERMZYN

Oi lowo egbogi aran atase ti o daju fun iparun awọn "ARỌN" buruku gbogbo lara enia, papa tabi ni pataki fun ARỌN lati lati tabi arọn kini a ti o ma mu idiwọ wa fun ẹgba ibeje obinrin lati loyun tabi ti o ma nba oyun jẹ lara Obinrin.




Bi si ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti ara a bidu Igba aya, ọfun, s s lẹhin bi ake tabi aran oju pẹlu Meji ir fẹ egbogi arọn yi osi ni gbogbo ilẹ Naijiria ja Işẹ rẹ si daju.

AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe o ti re ekọnọ ọwọ ati ẹsẹ rẹ daradara ki otẹ lo egbogi arọn yi gẹgẹni awọn Jaman ti o şe ti juwe lilo re o, Fun agbalagba ikan ni o wa fun Bere orişiri egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni şọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA*

No. 1,425 TUESDAY AUGUST 10, 1965 5-(2D)


## Iya Olọti Ologogoro

IBADAN:- Ninu ọsẹ to kọja yi ni Adajọ ile ẹjọ kekere ti Ibadan paṣẹ pe ki Obinrin kan Angelina Anthony ẹni ọdun mẹdọgbọn lọ fi Ponun mẹwa ati ṣile mẹwa £10, 10/) taran tabi ki o yara lọ fi ẹwon oṣu meji jura lafaraba lori ẹsun pe awọn Ọlopa ka oti Ogogoro moo lowo,

Ninu oro olopa to ba ẹdaran na ṣẹjọ ni o ti se alaye fun ile ẹjọ ni ọjọ kẹta oṣu yi ni awon olopa bẹrẹsi ni tu awon moto to nbo lati Eko tabi lati lo si oju ona Shagamu eyiti awọn olopa fi ri garawa oti Ogogoro ati galonu oti kan lowo obinrin na.

Nigbati Adajo ile ẹjo na bere lowọ obinrin odaran na pe njẹ o fẹbi ẹsun ti ile ẹjọ fi kan tabi ko jẹbi? Obinrin na si dahun pe on jẹbi ati pe ki Adajo ile ẹjo na ni oju anu rẹ si ni.

Adajọ ile ẹjọ na si p a ṣ e pe ki Obinrin Ologogoro na lọ fi ponun mẹwa abo (£10: 10/) tanran tabi ki o lọ si ẹwon oṣu meji Adajo i l e ẹjo na tun paṣẹ pe ki awon Ọlopa lo da Ogogoro na sonu patapata

# Ijọba Fẹ Gbe Ejọ Ọrẹdẹin Kuro Ni'jẹbu Ode ?

LATI OJU EWE KINI

maṣe gbọ ọrọ ti Ọgbẹni Oki gbe wa si iwaju rẹ, wipe ki awọn gbe ẹjọ apania ti Ijọba nba awọn enia kan ṣe ni Ijẹbu-Ode kuro ninu ile ẹjọ na ki awọn si wa ṣe e ni Ibadan.

Ọgbẹni Olu. Ayọọla ṣe alaye fun ile ẹjọ na wipe, ni Ijẹbu-Ode ni ẹjọ ti Ijọba nba awọn enia na ṣe nwọn si gbọdọ ṣe ẹjọ na ni Ijẹbu Ode ni ko si ohunti o le gbe ẹjọ na kuro gẹgẹbi ofin

Ọgbẹni Ayọọla tun sọ fun Ile ẹjọ na wipe ohunti o ba ṣẹlẹ ni Ijẹbu-Ode adajọ wa ni Ijẹbu-Ode awọn ni nwọn si le ṣe ẹjọ na ki iṣe ẹtọ gẹgẹbi ilana ofin iṣelu fun adajo Ibadan ki o wa ṣe ẹjo Ijẹbu Ode.

O tun sọ pẹlu wipe ki yio jẹ ohunti o dara wipe adajo Ijẹbu-Ode ṣe ẹjo ohunti o ba ṣẹlẹ ni Ibadan, nitoripe gbogbo awon nkan won yi ni nwon lodi si Ofin iṣelu gẹgẹbi ohunti won ti ko silẹ

Ni ipari oro rẹ, Ọgbẹni Olu. Ayoola wa ro ile ẹjo na wipe, ki o ko ẹbẹ ti Ọgbẹni Oki gbe wa si iwaju rẹ, nitoripe oro na mu ewu lowo o si lodi si idajo.

Ọgbẹni Olu Ayọọla tun rọ adajọ agba na lati ma gbọ ẹjọ ti Ọgbẹni Oki so wipe ki nwon gbe ẹjo na kuro niwaju adajo Ijẹbu-Ode nitoripe bi adajo ba ṣe bẹẹ ti o si gbo ẹbẹ Ọgbẹni Oki yio mu ewu idajo ododo lowo fun gbogbo awon adajo ati enia ni Orilẹ ede yi gẹgẹbi ohunti nwon ti ko silẹ

Adajo agba na, Ọgbẹni Adeyinka Morgan ti yẹ gbigbo ẹjo na si ola (oni) nigbati yio ṣe idajo bi o yẹ ki nwon gbe ẹjo na kuro ni Ijẹbu Ode tabi ko yẹ ki nwon gbe ejo na kuro.

LATI OJU EWE KINI

Adajọ ile ẹjọ na tun ṣe alaye pe nigbati o ti lọ fa ohunti owọ rẹ ko le gba yio san fun ọ lati duro fun ohunkohun ti yio ti ẹhin rẹ wa.

Aiyelabọla tun rọ ile ẹjọ na lati ni oju anu si on atipe on ko mọ pe iru ohunti ẹsun na yio da si on lọrun. O ni ki ile ẹjọ on da kun ni ni oju anu si on atipe on ki yio ṣe bẹ mọ.

Adajọ ile ẹjọ na si ṣe alaye ninu idajọ rẹ pe ko si oju anu kan ti on le ni si iru enia to pe ara rẹ ni Woli to tun jẹ wipe ole ni yio tun maa ja Adajọ na si paṣẹ pe ki Woli ole, na yara lọ fi ẹwọn oṣu mẹfa lọ jura ni afaraba.

Ninu ọrọ ti Agbẹjọro fun Ijọba ti sọ fun ile ẹjọ tẹlẹ ni o ti ṣe alaye pe Ayelabọla ṣa kuro ninu ọgba ẹwọn ti ilu Ọyọ eyiti o lodi si ofin ni ọjọ kini oṣu kẹje ọdun yi.

Nwọn ti sun gbogbo ẹjọ ọdaran kanna si ọjọ kẹtalelogun oṣu yi.

## Oye A Mọri O Adeniji

EKO:- Irohin ko to afajuba ni aṣeye iwuye alarinrin ti Oloye Adeniyi Coker Alamojuto ati Alaṣẹ Ọja Ijọba Ibilẹ Eko (Lagos City Council) ṣe ni ojọ keji oṣu yi ni Aafin Afinju Ọba Adeyinka Oyekan Keje Ẹsẹ awọn Oloye Onifila funfun ati awọn Oloye Abagbọn ati awọn Oloye ti Ọba fi Oye da ni ọla ati awọn bọrọkinni ati awọn oṣiṣẹ Ijọba Ibilẹ Eko fi paapa awọn ẹgbaagbeje Ọlọ-a ni o pe ṣọọṣọ ṣibẹ.

Lẹhin ti nwọn ti ṣe gbogbo eto iwuye na t a n n i Oloye na Adeniji Coker ati awọn O l o y e egbe rẹ ati awọn oloye onifila funfun awọn bi Oloye Ọmọ-Ọba Sẹnatọ Aminu Kọsọkọ Iṣọla Bajulaiye (Eletu-Odibo) Abudu Lamidi Kalefo Keji (Olumẹgbọn Ajaye) Ọ b a ni Koro Saba, Bajulaiye ati bebẹẹlọ ati awọn Alhaji Y. A. Disu Fasinro ati Ọkunrin ati awọn gbajumọ lọkunrin lobinrin ati awọn oṣiṣẹ.

Ijọba Ibilẹ Eko ati awọn ọlọja ati awọn ijọ ṣọọṣi rẹ ba ba a ko ẹyẹ alarinrin lọ si "agbara," rẹ, ni nomba 59 li a dugbo Jẹbba l' Ebute Metta. Lẹhin ti awọn ijọ si ti ṣe adura fun un tan, ni oloye na si wa fi oriṣiriṣi onjẹ adidun ati oriṣiriṣi ọti gidi tẹ gbogbo awọn alabaṣe ọjọ na lọrun ti ti di ọgan jọ ọjọ. Ọpọlọpọ awọn a alabaṣẹyẹ ọjọ na ati gbogbo awon ọloja obinrin ti nwon ro ti nwon si gba dedẹ ni nwon si nla ijo mora bi kokoro.

Ẹṣọ oloye na ga lola.

Amuyẹ rẹ si po pupo. O si mo ijo ajoyẹ jo pupo. Inawo ti oloye na si ṣe po pupo Iya- afin "aya" rẹ si se ẹṣọ bi ayaba. o si njo ti igba ti ayaba njo gbẹdu.

Awon alabaṣeyẹ ọjo na ti poju a ko si le daruko wọn lokookan. Oloye Adeniyi Coker, o ti lo waju, Oye a mo ri o.



Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos, Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 10/8/65